**Lakaye Oro**

Omọ ti ko ranti Ọlọrun Baba tabi iya rẹ bawo ni owo osu ṣe lo mọ lowọ, nigbati ko fi ewe iṣu tọ iṣu ti ko si fi ewe ọka tọ ọka esan nbẹ ki igbe.

# IROHIN IMOLE

MOTTO: IMOLE DE, OKUNKUN PARADA.

**Owe**

Abuwa ibaje ṣe bi ti on ni a nwi, aye buruku o ku afa fu, asọrọ pelẹ boju wo igbẹ, igbẹ ko nwi ẹniti a mba sọ lo nro ni kakiri.

Ebi npa ejo, ahun si nyan, ati ahun ati ejo ẹran jijẹ.

VOL. V No. 311 MONDAY JANUARY 8 — JANUARY 14 1962 KỌBỌ MEJI (2d)


# OWO ILE ẸKỌ GIGA TI SUN SOKE NI IPINLẸ IWỌ ORUN NAIJIRIA

A GBỌ IROHIN WIPE, NWỌN T FI OWO KUN IYE OWO TI NWỌN TI NSAN TELE RI FUN ILE EKỌ GIGA NI IPINLẸ IWỌ-ORUN (HIGH SCH. GRAMMAR SCHOOL, COLLEGE AND UNIVERSITY) GA SI OKE LATI IBẸRẸ ỌDUN NI.

Nwọn sọ wipe, dipo eyiti Ijọba fi ngba Pọnun mẹdogun lọwọ ọmọ kunrin fun ọdun kan, ti nwọn ngba Pọnun mẹwa lọwọ obinrin lọdun kan fun owo ile ẹkọ, nwọn o kuku sọ di Pọnun mẹdọgbọn, nitorina ẹru na yio di ẹru awọn Obi awọn ọmọ ti o nlọ si ile ẹkọ giga na. Ki nwọn si to bẹrẹ si lo ofin yi, o di ẹhin oṣu April lọdun 1962, ki awọn olukọ ba le ri aye lati tẹ mọ awọn ọmọ ile ẹkọ leti, nitoripe ki a ba le gbọ ẹrọ ẹnu awọn Obi ọmọ ti o nlọ si awọn ile ẹkọ Giga na.

Iwọnyi ni awọn ohun ti yio tun ṣẹlẹ nipa Ẹkọ ko ṣe ẹkọ. (a) Gbagbo awọn ilewe yio di ẹlẹkun rẹrẹ ni ilọpo meji tabi ilọpo mẹta. (b) Gbogbo awọn ile ẹkọ Giga yio bẹrẹ si gba ẹmọbinrin pẹlu awọn ọmọkunrin papọ nitori ki wọn le jumọ ni iru ẹkọ kanna.

(D). Dipo eyiti Olukọ kọkan ti o ti yege nkọ wọn ni Ẹkọ, nwọn o wa di meji meji. (e) Awọn Olukọ ti o ti yege ninu ẹkọ ipo keji (grade two) ni yio ma kọ wọn ni ẹkọ. (f) Ẹgbẹgbẹrun mẹdogun pọun ti Ijọba ti nsan fun ile ẹkọ awọn obinrin ati ẹgbarun fun ti Ọkunrin yio wa bẹ, ko si ni yi pada. (g) Ẹnikẹni ti o ba tun nfẹ ṣi ile ẹkọ titun yio ni lati fi ẹgbẹrun marun lelẹ pelu ile ẹkọ ti a kọ, ti o le ti o si ye koro, owo yẹn ni a o fi ṣe inawo awọn ohun elo ile ẹkọ na fun ọdun diẹ.

Owo na yio wa lọwọ Olusiro owo Ijọba. A si le gba owo yi pada lẹhin ti ile ẹkọ na ba ti fi ẹsẹ mulẹ.

4. Ṣugbọn ẹniti o ba kọ ile Ẹkọ fun ọmọkunrin, ko ni ri owo iranlọwọ gba titi Ijọba yio fi ṣe akiyesi rẹ fun ọdun marun.

## Adeniji Adele gba Ogbeni Bajulaiye ni Eletu Odibo Eko



Ẹniti a nwo niru aworan yi ni Ogbẹni Bajulaiye nigbati awọn Ẹbi rẹ mu lọ iwaju Alaiyeluwa Ọba Adeniji Adele Keji wipe on ni gbogbo awọn Ẹbi panupọ le lori lati yan si ipo Oye Eletu Odibo lati fi dipo Ologbe Amusa Gbadegẹsin ti oku. Ọba si fi tayọ-tayọ gba a nitori inu rẹ dun si, o si fi ọwọ fa a dide, ẹgunlọgọ awọn agbagba ati awọn Ijoye si jẹri si. Ọgbẹni Bajulaiye ni a nwo ni ikunlẹ niwaju Ọba Alaiyeluwa, Ọba lo jeko si ori nga to gbe ọwọ rẹ si oke. Lọjọ Satide to kọja ni wọn gbe Ade de lori ni Ẹnu Ọwa nilu Eko


Read The IROHIN IMỌLẸ every week. It is a Yoruba Weekly Paper that will provide you with more News more Pictures and more Fun. It will enlighten, entertain and inform you. Always read:-

IROHIN IMOLE

The most exciting controversial Yoruba Weekly Paper

# ỌRỌ OLOTU

## Ife inu rere si enia laiye alafia

Gẹgẹ bi ẹnyin Onkawe wa ti mọ pe, iṣẹ wa ni lati tọ enia si ọna ti o tọ ati ti o yẹ, papa lasiko ibẹrẹ Ọdun titun yi, nitorina ni a ṣe gbe Ọlọla Gomina Agba wa lẹsẹ nipa ọrọ ti o sọ ninu ikini ku ewu Ọdun Keresimesi ninu iwe wa ti ọsẹ yi. Ifẹ inu rere si enia laiye alafia, eyiti gbogbo awọn Kiriyo nia nwi, ododo ọrọ ni ọrọ wọn na kiṣe arosọ rara nitori pe ira awọn ọrọ miran wa ti o jẹ pe arosọ lasan ni, ti a si ma ka kun ododo, ti a ba ni ifẹ ati inu rere yi, on ni o le sọ ilẹ aiye yi di ohun ti o dara fun enia lati ma gbe, ti o ba ni inu rere, iwọ yio ma wa ọna kan lati ri pe, ti ẹnikeji rẹ dara, ṣugbọn lode ti o ni Onigbagbọ melo lo nwa ire fun ẹnikeji rẹ?

Ko si ifẹ ati inu rere lode oni mọ, ohun na ni o si nfa ti aiye fi di rudu-rudu, ti iwa ika si fi kun inu rẹ, gẹgẹ bi aigba Ọlọrun gbọ. Ko si otitọ tabi ododo mọ lode oni, ko si si ẹniti o afẹ lati ru ẹru fun ẹnikeji rẹ, Iwa imọ tara ẹni nikan ati ise okunkun ti gbode, onikaluku lo nsare bi on yio tiṣe le ẹni iwaju ba. Bi a ko ba lọ fi awọn iwa wọnyi silẹ tabi ti a ko ba ṣe bayi, a kiṣe Onigbagbọ tabi Musulumi.

Awa Onṣe Irohin Imọlẹ bẹ yin, ẹ jẹki a fi Igbagbọ wa mulẹ gbọingbọin, ki a si ma bọwọ fun awọn agba wa, ki a ri pe a pa ofin Ọlọrun mọ, gbogbo ẹnyin Onigbagbọ Naijiria nigbati ẹ ba nṣe iranti Ajọdun Ọdun Keresimesi, ẹ jọwọ ẹ ma ṣe ma sma gbagbe bi Ọdun na tiṣe sẹlẹ, ki ẹ si ma mọ ohun ti ẹ nṣe fun. Ki a to pari ẹsin ọrọ wa ti ọsẹ yi a fẹ ki gbogbo wa lọ ni ifẹ ati inu rere si enia, ki a si bẹru Oluwa pẹlu ofin rẹ.

## Olori Alufa fi Alufa agbegbe ile Binin han awon Ijo



Eniti a nwo ninu aṣọ funfun ti o wọ Agbada gereje ni Olori awọn Alufa kakiri ile Iwọ Orun Afirika, Eni ọwọ inlọ C. J. Patterson, on ni eniti o fi Ogbẹni Alufa Bishop Iwe han gbogbo Ijo nigbati won fi jẹ oye D i o c e s e titun fun agbegbe ile Binin Warri ati Asaba.

# Wọn tun fi Ọgb... jẹ Oye ni ilu Binin



### Awon Awujo Diocese nyo mo Bishop Iwe

Aworan ti a nwo yi ni aworan igbati awọn enia duro ni waju Ṣọọṣi ti nwọn si nyọ mọ Ọgbẹni Bishop Iwe lẹhin igbati wọn fi joye kan ti wọn npe ni Diocese.

Oye Diocese yi jẹ fun ti agbegbe ilu Binin, Warri ati Asaba, gbogbo awọn awujọ Diocese si bẹrẹ siyọ mọ Ọgbẹni Iwe, nwọn si ki ku orire oye ti wọn fi jẹ pẹlu ẹrin ati Ayọ.



# IGBESI AIYE MI NINU IGBO AILOPIN (APA 11)

Łati Qwọ:- SIMEON ADE. FATOKI (London)

Mo ki gbogbo ẹnyin Onkawe Irohin Imọlẹ pe ẹ ku ewu aisja ọdun Keresimesi ati ọdun titun, mo ki awọo ọmọ ẹgbẹ Imọlẹ Aiye na, Oluwa ko jẹki ọdun yabo fun gbogbo wa o, gbogbo ẹnyin to nlọ sile iwe Oluwa ko ran yin lọwọ, ẹ o ma ṣe dada ninu ẹkọ yin o, ẹ ma se binu pe ẹ ko ri apa konkanla itan mi ka lasiko, ipalẹmọ ọdun ti mo pamọ ni ko jẹ, ṣugbọn lati isisinyi ẹnyin yio ma ri ka dede pẹlu irohin aladun lati ilu Oyiubo. Apa konkanla itan na lọ bayi:-

Bi mo ti rin diẹ siwaju ni mo ngbọ iro ila aladun kan mo si tẹti silẹ dada lati gbọ, mo ro ni ọkan mi pe onilati jẹwipe ibiti ogbologbo agbọnrin yi sọ fun mi ni yi, ibi ti mo ti nro eyi lọwọ ni mo yọ si arin ibikan ti o tẹ pẹrẹsẹ, ibẹ si to iwọn ibuso meji yika. Nigbati mo rin de opin ilẹ yi mo ri ọna kan toro ti igbo fẹrẹdi tan, eyi yi ni ọna ti o lọ si ọrun rere, bi mo si ti ṣe tun wo ẹgbẹ ibiti ilu aladun yi ti nwa ni mo ri oju ọna nla kan ti o lọ si ọrun Apadi nibiti esu ti nṣe ọba wọn. Eyi mu mi mọ dajupe mo ti de ibiti mo nlọ. Mo ṣe akiyesi ohun meji pataki kan ni oju ọna mejeji yi, Awọn akiyesi na ni wipe awọn enia pọ ti wọn ngba ọna ti oto bi yi ti o si lọ si ọdọ Eṣu Ṣugbọn diẹ ni awọn ti nla na inu igbo ti olọ si ọrun rere yi. Nigbati mo wo bi enia ṣe pọ to ti onde arin ibiti mo nwi yi lojumọ wọn le ni ẹgbẹrun kan. Awọn wọnyi si ni awọn ti wọn nku ni ile aiye ti wọn si nlọ si ọrun. Nigbati mo wo gbogbo kini yi tan mo ya si ọna apa ọtun mo nlọ, nko rin jina pupọ ngibati mo ri aṣọ ti o la ọrun ati aiye si meji ni totọ, bi mo tiṣe ri inu mi dun pupọ mo kunlẹ mo bẹ Ọlọrun Ọba ki o ran mi lọwọ. mo si mu ororo ti Agbọnrin yi fun mi mo fi ra oju mi mo si gbe apo mi ka lẹ ni ẹgbẹ aṣọ funfun yi mo rọra lọ si idi aṣọ yi mo fi ẹnu ko mọ si bẹrẹsi sọrọ wujẹwujẹ si bayi pe:- "Iwọ Ọlọrun ti oni Aiye ti oni Ọrun ati ohun ti owa ninu wọn, iwọ ti oda ohun gbogbo ti owa ni aiye ti osi dami, iwọ ti o da ẹiyẹ ti osi da ẹranko, iwọ ti o da era ti o da kankan, iwọ ti o da omi okun ati ẹja inu won, ti o si fi enia ṣe ọga lori gbogbo ohun ti o da ni ile aiye, ki ṣepe bo ya a dara ju awọn Ẹranko tabi Igi lọ, ki ṣepe agbara wa po ju ti wọn lọ ṣugbọn ọgbọn ori ti wa loju tiwọn lọ. O fi ọgbọn si wa lori lati ma ṣe alakoso wọn.

Ọgbọn yi gan ni mo tun wa tọrọ loni yi, ọgbọn ti yio wu lo fun ilu mi, ile mi, Ẹbi mi, Obi mi, ati fun gbogbo enia, iru ọgbọn ti o fi fun ọba Selomọni ni ọjọ kini maṣai fi iru rẹ fun mi loni. Eniti o bati ni ọgbọn ti ni owo, ọla ati okiki ninu aiye, jọwọ maṣe jẹki awọn obi mi ku bayi lai fi mi rọpo wọn, anibi Ina ba ku a fi eru boju, bi ọgẹdẹ ba ku a fi ọmọ rọpo.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸJỌ

# Oba Gesi lo be Omo re wo



Ẹniti a nwo ninu sworan yi ni Alaiyeluwa Elisabẹti Keji Ọba Gẹsi, ti o mura ninu ẹwu oye rẹ nigboti o fẹ lọ bẹ ọmọ rẹ wo, eyi ni ọmọ ti o bi gbẹhin fun Duke of Edinburgh ọmọ na mbẹ lọdọ awọn Alagbatọ rẹ ninu afin Windsor Castle nigboro ilu London, nigbati Elisabẹth gbe ọmọ na, awọn Medal ti ọba fi ṣe ọṣọ si igba aiya ni ọmọ na mu dani ti o si nyọ.


BERE EGBOGI JAMANI AJIDEWE TỌNIKI TITUN TI O ṢẸṢẸ DE TI WỌN NPE NI:-

"DYNAMIREN" TONIKI

EGBOGI AJẸBIDAN FUN AGBALAGBA ỌKUNRIN GBOGBO




Dynamiren jẹ Ojulowo Egbogi Ajidewe haunhaun ti awọn Jamani ti nṣe wa fun tita ki ogun (War) ti awọn Gẹsi pẹlu wọn to ṣẹlẹ, Lẹhin igbana a ko ri irufẹ egbogi ajidewe ti o lagbara gidigidi ti iṣẹ rẹ si daju bẹ yẹn mọ ni ilu Naijiria, eyi lo mu wa ranṣẹ si awọn Ogbologbo Dọkita wa ni ilu Jamani pe ki wọn ṣe iwadi awọn elegbogi "Dynamiren" bi wọn ba si mbẹ laiye. Wọn si da esi pada wipe wọn nbẹ atipe egbogi na ti a nfẹ lọdọ wọn wa pẹlu. Eyi mu inu wa dun pupọ julọ nitoripe awọn Onibara wa mọ daju wipe kosi aṣanu ninu gbogbo egbogi wa rara. Ẹgbagbeje irufẹ rẹ wa kakiri ṣugbọn bi ti eleyi kọ Bi arẹ ara ba mu ọ, nigbakugba fun wahala tabi iṣẹ de ti o ko ba le jẹun daradara, tabi ki o ma le sun de wọn lọsan tabi loru tabi awọn "Iṣan ara rẹ gbogbo" ko ba ṣiṣẹ daradara arẹE-emi (breath) inu ko ba gunle dara kara to nitoripe iṣẹ tabi wahala ṣiṣe ko "NJẸ" fun wọn ailera gbogbo wọnyi ti ọjọ ori rẹ (age) ba ti kọja ọgbọn ọ d u n lọ si dede adọrin tabi jubẹ lọ mọ daja pe "DYNAMIREN" ni egbogi ti o nfẹ lati sọ ara rẹ di Ọtun patapata, oju rẹ a si jọlọ, ẹran ara re ti o ti hunjọ yio bẹrẹ si dan pada. Ara rẹ yio ma gbe kọnkọn nigba kugba "Arẹ" nigbakubga yio salọ patapata pẹlu Igbadun ati Alafia yio de si ọ.

Bere egbogi na ni Ṣọbu awọn:

NIGERIAN MEDICINE STORES
4, TINUBU STREET, LAGOS. PHONE: 20278.

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OṢHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
IṢẸ OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA

# ORO NIPA EWO

Lati Owo:- SAMUEL WOLI KOGBEREGBE

Enikẹni ti o ba yo ni yio ma ka e wọ wipe ko gbọdọ jẹ eleyi, bẹni awọn Imale sọ pe awọn ko gbọdọ jẹ Ẹlẹdẹ Irọ ni wọnyi jẹ ati baba eke, gbogbo ẹnyin Imalẹ ẹ maṣe sọ wipe ẹnyin ko gbọdọ jẹ Ẹlẹdẹ mọ. Nitoripe gbogbo ohun ti Ọlọrun da lo dara, ko si eyi to yẹ ki a kọ sile laijẹ, mimọ ni Ọlọrun, mimọ si ni gbogbo ẹranko ati ẹiye ti Ọlọrun da. E wo lo yẹ ki a kọ pe ko yẹ ka jẹ nmu ohun gbogbo ti Ọlọrun da?



Elomiran yio jẹ ẹlẹdẹ yio si wọ Ijọba orun ju ẹniti ko jẹ Ẹlẹdẹ lọ. E ma jẹ ka tun sọ nipa ti Ẹlẹdẹ mọ, ẹ jẹki a tọju iwa wa ati Irin ẹsẹ wa, ṣugbọn Iwa rẹ ati Iṣẹ rẹ bi o ti mu gbogbo ohun wọnyi ba ọ, nitorina tọju iwa rẹ bi iwa rẹ ko ba di o lọwọ ko si ẹnikẹni to le di na ire rẹ nile aiye. Jeremiah ori 4, ẹsẹ 18. Ko yẹ ka gbọkan le ọrẹ kan, nitori ọrẹ lo nsọ ema di ẹni e ṣte, Ha! Yẹ! enia kose fi nu han o jẹ lọ ṣọra rẹ, gbogbo enia lo dẹ gbe aiye daiye agula.

Eke ni gbogbo ẹnyin ti ẹ sọ wipe ka ma jẹ Ẹlẹdẹ mọ, ọpọlọpọ Alhaji lo sọ wipe Iwọ ko gbọdọ jẹ Ẹlẹdẹ mọ nwọn si nje Bọta ati Sọsej, o si sọ wipe iwọ ko gbọdọ jẹ Ẹlẹdẹ rara. Ṣe bota ati sọseji ti iwọ nje ṣe ororo agbari rẹ ni wọn fi ṣe bọta na ti iwọ fi nje wọn?

Nitorina ohunkohun ti a ba nta lọja ni ki ẹ ma jẹ lai bere ohun kan nitoripe ti Oluwa ni ile ati ẹkun Rẹ.

(I) Kọrinti, ori 10, ẹsẹ 25. Nitorina irọ ni awọn Imale npa, nwọn a ma wipe Oluwa ni awọn ko gbọdọ jẹ Ẹlẹdẹ, mo fẹ sọ fun yin wipe Alhaji to gba iyawo Tiamiyu, ti o si bẹrẹ si di Tira Ika, o si ma purọ pẹlu Ika yipada si Ọlọrun, ṣe Ọlọrun yio fi ẹjọ Alhaji Ika, silẹ laiko da, ko ma wa da ẹjọ ẹniti o nje Ẹlẹdẹ?

Nitorina mo wi ni iyara mi pe, eke ni gbogbo enia. Kili emi o san fun Oluwa nitori gbogbo ore rẹ si mi. Psalmu, 116, ẹsẹ, 11. Ẹyin yio gbọ ọrọ iyokun to ba di ọsẹ to nbọ, ki ẹyin woo, ẹnyin yio si ri ninu iwe Irohin Imọlẹ. Mo ki olotun, ati akọwe, ati gbogbo ẹnyin olutẹ iwe na. Jesu yio ran yin lọwọ.

# Owe Ile Yoruba

Igbin ka, ka, ka, ebiti ka, ka, ṣugbọn ebiti ti ko gboju ko ni pa igbin rara, patako. Ẹfọn ka, ka, ka, lo nta aja ... mbọ Omi tuta lo njade lati ẹnu ẹja wa. ikun njẹpa, o nrẹdi, ko mọ p... to dun lo npani

# Bi Olorun ko Pani Oba ko Ie Pani

Lati Ọwọ:- Alliu. Ọla. Buraimoh

Nọ 133 Ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye

Ni aiye atijọ, awọn ọkunrin meji kan wa ni ilu kan, Orukọ ekini a ma jẹ B'ọlọrunkopa-Ọbakolepani, ekeji a ma jẹ B,ọbakopani-Ọlọrunkolepani Ọba kan gbọ orukọ awọn ọkunrin wọnyi, osi ranṣẹ pe wọn, nigbati wọn de ọdọ re, o bere orukọ wọn. Ekini ni a ma jẹ BiỌlọrun-kopani-Ọbakolepani ekeji ni on a ma jẹ BiỌbakopani-Ọlọrunkolepani. Bẹni Ọba mu aṣọ funfun fun B'Ọlọrun-ko panı, osi fi aṣọ dudu o fi fun B'Ọba kopani- Ọlọrun ko pani, osi ran wọn jade; Ṣugbọn ki oto ran wọn jade o ti ran tafatafa kan lati lọ sapamọ de wọn ninu igbẹ, wipe bi awọn Ọkunrin meji yi ba mbọ ki o tafa lu alaṣọ funfun, ki o si pa a.

Nigbati awọn Ọkunrin wọnyi jade kuro niwaju Ọba, B'Ọba kopani bẹrẹ si sọ wipe, aṣọ funfun ni on fẹ ṣugbọn Ọba fi dudu fun on; O si sọ fun B'Ọlọrun kopani- pe ki o jẹ ki nwọn ki oṣe paṣiparọ eyini fi funfun tirẹ fun B'Ọba kopani, osi gba dudu tirẹ.

Bi nwọn si ti rin siwaju diẹ ni nwọn ri ti ọfa ba B'Ọba kopani; lojukanna o si ku. Bẹni Bi Ọlọrun kopani sare pada tọ Ọba lọ, o sọ gbogbo ohun ti nwọn ṣe fun Ọba, ati bi nwọn si ti pa ekeji on.

Ọba na si dahun wiwe, otitọ li orukọ rẹ; B'Ọlọrun kobapani ko si ẹniti o le pani Ọba si da Ile rẹ meji, o da ọna rẹ si meji, o fi fun Ọkunrin na.

Ẹkọ inu itan yi pin si ọna meji, ekinni ni wipe Ẹni ti Ọlọrun ko bapa kosi ẹni ti ole pa a; Ekeji nipe oyẹ ki a ma ni itẹlọrun lori nkan kinkan ti aba mu fun wa. Abọ itan mi ni yi o.


# MOGBAYI COUGH MIXTURE




Mogbayi Cough Mixture jẹ Ogun Ikọ pataki ti a ṣe ni aṣepe lati wo awọn Ikọ origirisi san ni kiakia. O dara fun Ikọ agbalagba ati Ikọ ọmọde bẹni o si tun dara fun Ikọ ọmọ ọwọ pẹlu.

O dara pupọ ju gbogbo ogun Ikọ yoku lọ. O dara fun awọn arun Ikọ wọnyi, Ikọ ti o ma nba enia ni ohun, iko ti o ma npọn enia loju, Ikọ ti ki jẹ ki enia sun dada, Ikọ ti o ma ndun enia lẹgbẹ, Ikọ ti o ma nta enia ni aya, Ikọ ti o ma nfa Ẹfọri, Ikọ ti o ma nfa arọ ba ara, Ikọ ti o nmu ki enia ma pọ ẹjẹ, ati awọn Aisan miran ti wọn somọ Ikọ bi aiperi, oyi oto.

Mogbayi Cough Mixture yi dara pupọ fun ẹnyin ti Ikọ nyọ lẹnu, Ẹ ma ṣe ṣahun fun alafia ara yin, alafia ni opin ọrọ ijafara ni ewu pupọ, tete lọ ra Igo kan. Mogbayi Cough Mixture, yio wa ni ile itaja Egbogi ti o wa ni adugbo rẹ, Igo kan rẹ jọ 2/6d' a rapọ rẹ jẹ 24/-:)

**LILO RE:-**

Ọmọ oṣu mẹta—Idaji ṣibi 'tii kan ni wakati mẹtamẹta
Ọmọ oṣu mẹta si mejila:- Ṣibi tii kan nigba mẹta lojojumọ
Ọmọ ọdun kan si mẹfa.- Ṣibi tii meji nigba mẹta lojumọ
Agbalagba————Ṣibi Imukọ kan nigba mẹta lojumọ

*Whoesale Distributors:-*

A. K. KARIMU ANJOLA & BROTHER

6, Balogun Street West
Lagos, Nigeria.
Phone 22516.

34, Docemo Street,
Lagos.
Phone 24247.

# Amoran fun awon Imole Oro

LATI ỌWỌ:- ỌMỌ ORO GAN

Angbọ ninu itan wipe o ti to nkan bi i r a n kẹrin ti ẹsin Imale ti de ilu Oro, iyẹn ni wipe o ti to bi ọgọrun mẹrin Ọdun ti I m a l e akọkọ ti wọ ilu Oro lati adugbo kan ti a npe ni Isalẹmọle n i b i t i wọn si njẹ Imamu si titi di ode oni. A ko le sọ pupọ nipa awọn igba ti o ti kọja gẹgẹ bi wọn tiṣe ntan ẹsin yi ba, ṣugbọn eyi ti o da ju ni wipe agbara egbogi ati orukọ awọn alujannu ni awọn Alufa igba na nlo l a t i ma ṣẹgun ogun ati ẹbọra buburu ti awọn Keferi igbana ti wọn si fi nyi wọn si inu ẹsin tuntun ti wọn. Nipa bayi, a mọ daju wipe kiṣe nipa alaye tabi wasu pupọ, ni awọn enia na fi gba ẹsin Imale, bi ko ṣe nipa adura awọn Alufa igbana ati wahala wọn.

Sugbọn nigbati o wa ya ti awọn Imale ti fi ẹsẹ ẹsin wọn mulẹ dada ni Ọtun—Oro ati Oke—Ọla, ti awọn enia jankan-jankan ninu Keferi si ti gba fun wọn tan ti ẹnikẹni si nfi jijẹ Imale ati orukọ rẹ ṣe fari, ni Ọgbẹni kan Olowo Olokiki a t i gbajumọ, oloju ti a npe ni Aransi Okoko wa mu awọn A g u d a wọ ilu na. Lati igba ti awọn Aguda ti gbe ẹsin wọn de O r o ni wọn ti fi ọgbọn ati eto ile iwe lelẹ. Ọpọlọpọ awọn ọmọ si da si ibẹ ni Kiriyo ati Imale, debe wipe ni ẹhin ọdun diẹ, o fẹrẹ ma si Imale kan ni igboro Ọtun Oro mọ. Ni gbogbo akoko yi Oke-Ọla duro ṣinṣin lori Imale tirẹ, bakanna si ni wọn wa titi di ọjọ oni.

Ni arin igbati awọn ara O r o nyi pada si inu ẹsin Aguda yi ni Ọdọmọkunrin Alufa kan Adamọ Adeyiọla wa mu ọgbọn wa pe, ayafi ki awọn na da ilewe ti wọn silẹ, ni o le yọ wọn kuro ninu adanwo ti wọn bọ si yi, awọn Alufa ti ọlọna a t i j ọ tako amọran yi, ṣugbọn awọn ọjọgbọn gẹgẹ bi Abdu Rahimi ni Isalẹ-mọle Sulamọna Akọshile ni Oke-Ode ati Mọmọdu Ajisafẹ ni Oke Ọla gba amọran yi, wọn si b ẹ r ẹ si nise wahala lati mu ero rere yi ṣẹ. Awọn Aguda binu dele, wọn sa ipa wọn gidigidi lati ri wipe, Ile Iwe Imale ko ni sẹlẹ, nitoripe wọn ti mọ pe ninu ada silẹ Ile-Iwe Imale ni iṣubu ti wọn wa.

Dida silẹ ile Iwe yi mu ki awọn ọmọ Imọle gbogbo duro sinsin si inu ẹsin wọn, wọn ko si yi pada si Ijọ Aguda mọ, lẹsẹ kanna ti awọn Aguda ni eyi ni wọn ba tun gba ọna miran lati ma yi awọn enia si ẹsin wa eyi si ni nipa dida ẹgbẹ kan silẹ ti wọn npe ni Ajagun lati ma fi ọna owo ati owo tar awọn ti ko ni lọwọ si inu ẹsin wọn. Nigbati awọn Imale si tun ri eyi, ni wọn ba tun lọ gba Ọdọmọdekunrin Alufa kan ti orukọ rẹ njẹ Usẹni lati ma wa ṣewaṣu fun wọn, Oniwasu titun yi si fi gbigbona wasu ati alaye rẹ mi ilu jigijigi depo wipe awọn A g u d a fẹrẹ ma le lọ si ile isin wọn mọ.

WO IYOKU NI OJU EWE IKEJE.

# Onibode awon Arsenal ni Ilu Oyinbo



Ọkunrin ti a nwe ti o gbe okiti alagada ti o si fi gba bọlu ninu aworan yi, jẹ Onibode (G o a l e r) fun awọn ẹgbẹ elere bọlu (Ball) Afẹsẹgba kan ti a npe ni Arsenal nilu Oyinbo, a si gbọ wipe, ko si elere bọlu kan ti o le bori wọn ninu ere na.


BERE OJULOWO EGBOGI AWON FARANSE TI A NPE NI:-

## "UROXAL"

Fun riọju tabi fifọ Apo Ile Itọ Kidney-Bladder fun Ọkunrin ati Obinrin bi awọn amodi wọnyi ba nyọ ọ lẹnu Ẹhin didun eri ile tabi itọ-jijo enia, itọ rirun, rukuruku Pipọn tabi riruo, lakuregbe, Ibara di wiwo, orunkun, owọ, ẹsẹ Ejika wiwu tabi riro.



Ara sisan, titobiju, aiko le gbe ara kọnkọn tabi kiakia, didaji loru nigbakugbe, ati orişirişi awọn aisan tabi amodi ba wọnyi ni egbogi ajẹbidan yi yio wo san lara rẹ ni kiakia ti alafia yio si de si ọ. Meji rẹ ko si ni Ilu Naijiria nitorina ṣọra ki awọn eleru tabi awọn Oni rọbirọbi ma ta orişi omiran ti ko ni lari fun ọ, mase gba a rara o! Owo rẹ jẹ Sile Mẹfa abọ 6/6d owo ọkọ sile meji abọ (2/ 6d)

Bere Egbogi yi ni Ṣọbu awọn Saro ti wọn npe ni:-

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street, Lagos, Nigeria**
**Phone: 22878 (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMIST
WAKEMAN STREET, YABA PHONE: 22878

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET, OSHOGBO.

ATI NI AWỌN ṢỌBU IBADAN:-
ISE OLODUMARE DISPENSARY OKE-BỌLA



DIRECT ALL YOUR PRINTING JOBS TO:—

## MODUPE PRINTING PRESS

16, BAMGBOSE STREET LAGOS

Phone: 21985

# *ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE*

## Igbesi Aiye mi ninu igbo Ironupiwada (APA 1)

LATI ỌWỌ:— TAJUDEEN, A. ADEBOUN.
NO. 49, ỌMỌ ẸGBẸ IMỌLẸ AIYE.
ALIAS— APẸKOTOJẸUN KO NI JẸ IBAJẸ

Ọdẹ ni Baba mi nṣe, lati kekere ni mo si ti ma nba baba mi lọ si Igbo Ọdẹ, n k o si ju ọmọ ọdun mẹfa nigbati baba mi ti nkọ mi ni Ibọn yin, s u g b ọ n nigbati mo fi ma to ọmọ ọdun mẹwa, mo ti npa ẹran bi, Ẹtu, Agbọnrin Igala ati agbalagbo. Ẹnyin ọrẹ mi gẹgẹbi ẹyin na ti mọ tẹlẹ pe, ọmọṣẹ mbọ wa di Ọga, nigbati mo fi ma to ọmọ ọdun mẹdogun, mo ti npa ẹran nlanla bi, Erin, Ẹfọn ati Kinniun. Bi mo ti sọ fun yin siwaju pe Ọ d ẹ hanunhanun ni Baba mi. Ni oru ọjọ kan Baba mi dide, o gbe Ibọn rẹ, o si gbe Ina Ọdẹ rẹ siwaju, o mu apo Ọdẹ rẹ, o ko Ẹtu Ibọn si inu rẹ, o si mu Ikoko rẹ sinu rẹ pẹlu.

Bi o ti ṣe tan, bẹni o jimi, nitori mo ti sun ni ọjọ na, ṣugbọn jiji ti o jimi yi ko jẹ ki orun da ni oju mi, ẹ mẹta ni mo si takiti lọna oko Ọdẹ na ki oju mi to la, nigbati o ṣe ade oko Ọdẹ na, bi a si ti de bẹ ni b a b a mi tanna Ọdẹ rẹ siwaju bi awọn Ọdẹ ti ma nṣe, ko pẹ ti Baba tanna Ọdẹ rẹ, ni angburo awọn Odugbọ ti wọn nfo lati ori igi kan si ori igi keji Baba mi sọ wọn dada o si tanna siwọn loju, mo si y i n Ibọn siwọn, Ibọn mi si ba ọkan ninu wọn, eyi ni a kọ pa ẹran wa ni alẹ ọjọ na, mo si ju si apo Ọdẹ Baba mi. A nlọ ko pẹ lẹhin na ni Baba mi mu Ikoko taba rẹ, o si sana si, bi o si ti nfa Ikoko taba rẹ na ni a dede gbọ ohun kan ti o wipe "Awọn olorun wọnyi ko ni jẹ ki enia sun l o r u" ati ni ọsan, bi o ti wi eyi ni, Baba mi tubọ nfa Ikoko rẹ lọ. Nigbati o ka lara tan o jade si wa. Nigbati mo ri, ẹru ba mi pupọ, nitori pe, ọmọde ko le ri ẹru ko ma ba, bi Ẹbọra na ti wi gbogbo ti ẹnu rẹ tan, B a b a mi ko bikita si rara, o nfa Ikoko t a b a rẹ lọ ni ṣa, nigbati Ẹbọra yi ri pe Baba mi ko da ọwọ Ikoko taba rẹ duro.

O fi tagbaratagbara ki gbe pe, tani Iwọ nṣe Baba mi si da lohun pe, Emi ọmọ enia, ero ọkan mi ni pe, Ẹbọra yi yio ba Baba mi ja ni, ṣugbọn depo eyi o wo Baba mi titi o ni, Iwọ ọmọ enia, Jọwọ ma sai sọ ẹniti Iwọ jẹ fun mi. Nigbati o wi bayi tan, Baba mi da lohun pe, on ni ẹniti o r u k ọ rẹ Apẹkunjoye, ṣugbọn tani Iwọ nṣe, Ẹbọra yi da hun pe on ni Ẹbọra inu Awusa ẹniti orukọ rẹ njẹ Oni-Surukonibamọ Laiye.

Ẹyin Onkawe mi ẹ o ma gbọ Itumọ orukọ mejeji yi niwaju. Bayi ni mo ma duro lọsẹ yi ṣugbọn lagbara Ọlọrun ẹ o ma gbadun mi siwaju, ki Oluwa Olodunmare sọ wa di ọsẹ na.

Jọwọ ma sai ma ka i w e Oloyin mọmọ yi lọsọsẹ, Iwe Irohin Imọlẹ kun fun ọgbọn ati oye, ki Ọlọrun ma g b e Ire wa kọja wa o, Ọlọrun ko ni fi kọbọ meji wọn yin o. Amin. Mo dupẹ lọwọ Olotu, mo tun ki gbogbo ẹnyin [illegible] mi ti o jẹ ọmọ Ẹgbẹ Imọlẹ Aiye, evi ti o wa ni abẹ Irohin Imọlẹ pe, ẹ ku Orire ẹ ku [illegible] a l a j a Ọdun Keresimesi o. A o ṣe ọpọ Ọdun na laiye o Amin. Iwaju ni ọpa ẹbiti nre si iwaju ẹ o ma lọ o, Ọkọ Ọba ko ni sa yin lọṣẹ o Amin.

## Hausa kan ro wipe, Iku yani lara ju esin lo

EKO:— Ọkunrin Hausa kan ti o njẹ Dan Baba ti n ṣ e aisan iwora lati bi iwọn oṣu kan sẹhin, ko gbadun ara rẹ, gbogbo ara lo ndun, ko le sun, ko le wo, ko ri enia setọju rẹ, ko bi ọmọ, ko ni ara tabi iyekan. O wa ọ n a ti o le gbe gba ko ri, o wa gba ero bi on yio ti ṣe, awọn alabagbe rẹ gba ni amọran wipe ki o gbe ara rẹ lọ sile Alaisan, ati pe lọfẹ ni nwọn o tọju rẹ, Dan Baba, o si mu ara rẹ lọ sile Iwosan.

**Ki won** to da lohun, arẹ ti fẹrẹ mu Onisẹda Nwọn ni **ki o** lọ wa igo kekere kan wa, wọn si rọ e g b o g i diẹ s i n u rẹ, wọn si ṣe ikilọ fun bayi wipe, gba o! ṣibi ti won fi nmu **omi** gbona Tii ni ki o ma fi mu ọkan ni owurọ ati ọkan ni aṣalẹ Bi Hausa na ti gba egbogi yi tan, o wo o, o wipe, emi ti gbogbo ara ti ndun mi, ti nko le sun ti nko le wo, o wa jẹ wipe sibi kekere ni yio wa fun mi ni alafia. Kai! o gbe gbogbo egbogi na, o si da si ẹnu lẹkan soso, ko iti rin de Ita Tinubu, ti o ti ṣubu lulẹ, ti o si ku bamubamu, o h u n ti a gbọ w i p e o sọ gbẹhin wipe "Yiowa"

---

## Omoba Margaret ati omo re ko lo si Afin oko re



Awọn ti a nwo ninu aworan yi ni Ọmọba Margaret ati ọkọ rẹ ti nwọn gbe ọ m ọ titun ti wọn ṣẹṣẹ bi dani, nigbati nwọn **nko** lọ si ile Afin ibiti ọkọ rẹ Lord Snowdon ati Margaret yio ma gbe ni Afin Kensington. Ninu Afin Clarence ni iyawo ti ngbe ri, ṣugbọn nisisiyi o ngbe ọmọ titun na, ti o ti gba o r u k ọ yi, Viscount Linley lati ọwọ Ọba Alaiyeluwa ti iṣe ẹgbọn Iya rẹ.

# ẹni Bişọbu Iwe





## Awon egbe ako rin nko-rin fun Bishop Iwe

Ninu aworan yi ni a gbe ti ri awọn Ọmọ Ẹgbẹ Akọrin ile Isin ti awọn nda gbẹdu orin ayọ ni iranti Oye Diocese titun ti wọn fi Ọgbẹni B i s h o p Iwe jẹ gbogbo wọn si nu iwe orin dani.

## Owe

Adaba nfogede o ṣe bi ẹleyẹle ko gbọ, Ẹlẹyẹle gbọ, ṣugbọn ara lo nre.

Idoyi ko n p a kẹkẹ, apa ọmọde ko le ka Igi Ose nge ni yio ma do-yi ka'


## KERE O! AKIYESI PATAKI

Awa na le jeri wipe ojulowo haunnaun Egbogi gidi ni LEOPILLS. Awa na nlo ni ilu Gold Coast (Ankara) Ghana pẹlu, meji rẹ kosi ninu gbogbo orişirişi Egbogi kakiri ilu Naijiria.




### Irohin kakiri Igboro Ilu Eko

Bẹna ni ẹwẹ ni Igboro Ilu Eko, Irohin ti o wa lẹnu gbogbo enia. tọmọde ti agba ni asiko yi ti wọn si fi ṣe ọrọ ati orin larin ara won je nipa ti Egbogi Jamani olokiki yi ti wọn npe ni LEOPILLS.

Imọran awọn Dọkita Oyinbo ti wọn ṣe iwadi Egbogi LEOPILLS yi kan sọ wipe bi o ti lagbara to, ti o jẹ ojulowo giriki ati atametase fun iwosan JẸDIJẸDI bi o ti wu ki ọjọ rẹ pẹ to bẹna ni awọn le tun le fi ọwọ sọya tabi ṣe iletri fun gbogbo awọn ti amodi tabi a san bi Akọ Inarun, Lakuregbe, Ẹjẹ didu lara, Arun Ẹdọki Iju, Igbẹsise, tabi Aikẹri Igbọnsẹ dede, Inu rirun nigbakugba Ara wiwo, Ẹsanri, Ẹhin didun, Ojusi san tabi aiko riran kedere. Kokoro buruku lara, Osi inu Onigbameji, ati orişirişi arun miran gbogbo pẹlu "Wipe" wọn yio ri alafia ni kiakia ti wọn ba nlo egbogi LEOPILLS ntorpe a si tun ma tun ẹjẹ ṣe lara enia nipa sisọ di ọtun patapata.

ṢE IRANTI PE ALAFIA NI OGUN ỌRỌ IJAFARA SI LEWU PẸLU (POSTAGE 1/9) Egbogi Leopills:- Igo nla şile mẹfa pere ni, Igo kekere şile meta pere ni.

Bere ojulowo Egbogi Ominira fun orişirişi amodi ti o ba fe ni Ṣọbu awọn:-

Waterloo Medicine Stores 8, Palm Church Street, P. O. Box 333. Lagos Nigeria Phone: 22878. ati pẹlu ni ṣọbu ara binrin Mrs C. O. Babajide n e a r Health Office Ibadan ati ni Abimbola Medicine Stores B29 Okesha Street, Ilesha Bisale Medicine Stores. British & Foreigh Medicene (Dealer) S. W. 6/458 AGBOJO STREET IBADAN N.

AKIYESI:- Ri daju gbangba wipe Ṣọbu ti w ọ n nta lo gbe ranṣẹ lọ ra, bi ẹkọ awọn ẹlomiran yio fi ERU lọ ta adamọdi tabi orişi omiran fun ọ o, mişe gba rara


O BẸRẸ LATI OJU EWE KARUN

Ọkan awọn ọdọmọkunrin wọn si ko balẹ, awọn agba papa ko le tẹle ofin Ṣọşi mọ gẹgẹbi o ti şe wi, wọn bẹrẹ si ni ni l a r a, oju ọkan lo yatọ si ofin wọn ni ireti bi o tile ri ko ri. O wa şeni ni anu wipe lẹhin iku asiwaju awọn Imole Alhaji Suleman Akọsile, arẹ ọkan wa ba awọn ara Oro nipa ẹsin I m a l e, a ko gbọ orukọ ẹgbẹ Mashorud-Deen ni ita mọ, wọn wa fi ẹsin silẹ, wọn b ẹ r ẹ si ba ara w ọ n ja si nkan pẹpẹpẹ ti ile aiye. Ọpẹlọpẹ Mukadamu Akọshile ti ko fi wọn silẹ n i g b a kan, on lo jẹ ki ama ri oju ọrọ yan diẹ diẹ. A ko gbọ ẹsun kankan nipa Mọkaranta wọn mọ wọn nparọ ni o, wọn ko pa rọ si ni o, wọn mọ kewu ni o, wọn ko mọ ni o. ako mọ mọ Mọsalasi ti Akọshile agba bẹrẹ ki otoku, ko ni okiki mọ.

WO IYOKU NI OJU EWE KẸJỌ

## GREETINGS

Thanking All Our Relatives Friends, & Customers Far & Near For Their Past Support & Kind Patronage May Riches Knock at Our Door Throughout The NEW YEAR 1962.

**J. B. Crownson Odujobi & Sons**
**MEDICAL HERBALIST**

TOP FLOOR 16, BAMGBOSE STREET
2nd JANUARY 1962. LAGOS


# Oloye Osula nyo mo Alufa Iwe lehin Isin



Awon ti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Lawani Osula nigbati o nyọ mọ Bishop Agori Iwe lẹhin igbati wọn pari Isin Oye fi wọn ti Iwe jẹ lọjọ Alaruba Ọsẹ tokọja ni Ilu Benin.


# Owo eni lafi tun iwa eni se

Bi alowolọwọ ba nda ọ lamu, bi airọmọbi mba ọ lọkan jẹ, tabi airiṣẹṣe lo nyọọ lẹnu, tabi o tilẹ nṣiṣẹ na owo iṣẹ na ko duro lọwọ rẹ. Tabi awọn Ọmọraiye ko jẹ ki o gbadun igbesi aiye rẹ ni gbogbo ọna kọna.

Ọkọ rere tabi aya rere lo njọ ọ niya. Tabi amubọ ọkọ tabi ti aya, tabi ọja ti o nta ko lọ dede, tabi ohun miran lo mba ọ lọkan jẹ ni gbogbo ọjọ.

Mọ daju wipe dẹdẹ lo kọkọ bẹrẹ. Ki o si tun ọna rẹ ṣe, Kọwe pẹlu Ṣile Mẹwa abọ (10/6) pẹlu Sitampu oni tọrọ (3d Stamp) fun ohun to fa ati atunṣe adanwo na lọdọ:-

AWORAWỌ
16, MỌLẸYẸ STREET
P. O. BOX 165 YABA - NIGERIA


Printed and Published by MODUPE PRINTING PRESS 56, Bamgbose Street Lagos Phone 21985 Olotu E. A. Adenrẹ. 51, Tejuoşho Street, Surulere YABA.

O BẸRẸ LATI OJU EWE KETA

jọwọ masai jẹki awọn Obi mi le fi mi rọpo ni igba ogbo wọn. Jẹki nle gbe oruko wọ yọ ninu yi, ọgbọ ti emi yio fi ma se afakoso awon enia rẹ, Ilu mi ati eyiti ma fi mọ iwọ Olọrun lọkan ni mo nbere jọwọ masai se fun mi ki osi sọ mi di titẹ ni ọjọ aiye mi.

Bayi ni mo sọ ti mo si fi ibi aṣọ yi sile ti mo lọ duro ro ni ọkankan ko si pẹ ju nkanbi wakati meji lo nigbati mo gbo ohun nla yi ti onfi agbara yi fun mi ti ori mi si n di ti ọlọgbọn ni ẹsẹkẹsẹ ko si E d e ti emi ko gbo mọ ni Ile aiye, Mo wo ara mi ko yi pada ṣugbọn mo mọ pe ki ni kan asiṣe lori mi. Mo dupẹ ni ọwọ Ọlọrun mo si tun kunlẹ mo dupẹ mo si gbadura. Nigbati mo se eyi tan mo tun gbe apo mi mo kọri si Ilu mi ti mo ti wa, Bi mo se nlọ ni Inu mi ndun ti mo si nyin Ọlọrun logo.

## AMỌRAN FUN AWỌN IMALE ORO

O BẸRẸ LATI OJU EWE KEJE

Ikore ti wọn nta ni ọdọdun ko ṣe na si ọna ti Ọlọrun mọ ti aiye lasan ni wọn t u n nfi gbọ kiri. Anu ṣe mi. ọkan mi bajẹ, iṣẹ ti awọn enia nlanla ṣe kalẹ ni nwọn fẹ ko olugboro ti lati lu fọ, Wasi Inu awẹ ni Eko, ko ṣe ṣe mọ, kaka ki okiki ma gboro, nṣe lo nlọ si ilẹ, Imamu Salawu ni Oke Ola a fẹ gbọ ohun yin Alufa Kuranga, ẹ ma ṣe dakẹ, Aminu Megida Ọlọrun ko jẹ ki ẹ pẹ fun ara wa, ija Oro pẹlu Oke Ola, o to pipari ẹ ma ṣe wo wọn ni iran. Bi a gba ilẹ bi a gba oke, ki a gba ọja tan ki a tun gba omiran si, aiye ni a ba gbogbo rẹ, aiye si ni a o fi si lọ

Ẹbọ sokoto ki a dini mọ bajẹ, inu Onigbagbọ ndun si aiko gbọ ohun ara wa mọ. Ẹ dakẹ ẹ nwo iran, iṣẹ ti awọn baba yin ṣe kalẹ ki e ma se bajẹ, ko si ọmọ Oro kan ni ile Kewu Ilimi mọ. Esin ọtọ, Iṣelu ọtọ, ẹ jẹ ka jọ ma ṣe adini lọ, ki a fi ohun ti nṣe ti Sisari fun Sisari ki a si fi ti Ọlọrun fun Ọlọrun, Owo ti anri ni Ikore ọdọdun, o to ki a fi kọ ile Tiṣa (Teacher) si Mọgaranta, ki a kọ ile isin Mọsalasi si ọgba Oro Grammar School fun anfani awọn ọmọ Imale ni ibẹ, ki a si bẹrẹ Muslim College ni ilu Oro. Eyi n i k a n ni o le gbawa ni ọjọ iwaju ti ko ni sọ awọn ọmọ wa di ero ẹhin ninu ilu awujọ Oro.


BERE OJULOWO EGBOGI WỌNYI:-

### "Congreve Female Remedy"

Gbogbonse fun Itoju tabi Ajo Obinrin fun Inu riru Ibadi riro tabi gige nigbakugba, ati orişirişi arun tabi amọdi ti o ma nyọ Obinrin lẹnu ni Inu nigbakugba.

### "Collomack"

Egbogi awọn Jamani ti o dara julọ fun Itanpara, awọ ẸSẸ lile, Igbado ẹsẹ ti ki jẹki enia le wọ bata (Corncure) ati orişirişi arun Ẹsẹ miran pẹlu ni.

### "Mackctal"

Atamatase Egbogi awọn Jamani fun orişirişi amodi "ETI" riro tabi didun fun ọmọde ati agbalagba bi o ti wun ki ọjọ rẹ ti pẹ to yio ṣe iwosan rẹ ni kiakia.

### "Meduprival"

Ojulowo egbogi awọn ara ilu Tatanbulu fun iwosan ni kiakia gbogbo amodi tabi OTUTU Agbari, Igba aiya Ọna-ọfun, Imu tutu tabi ti o ma nsomi bi ikun nigbakugba. Kẹlẹbẹ ọna ọfun tabi agbari hiha, amuran ati orişirişi amodi miran gbogbo ti ibẹrẹ rẹ jẹ otutu. Bere ti Omode tabi ti agbalagba wọn yatọ nipa agbara wọn ni o

Bere ni Ṣọbu:—

**Waterloo Medicine Stores**
**8, Palmchurch Street Lagos,**
**Phone: 22878 Nigeria, (Oja ita Faji)**

ADEDUN CHEMISTS
4, WAKEMAN STREET YABA

WATERLOO MEDICINE STORES
11A, FAGBEWESA STREET OṢHOGBO